# ENMO RE ! ISU ABAMI NILU ABAKALIKI



SEE YOU PAY THE CORRECT PRICE.

ELETI OFẸ
A-NJU-WỌN KO SE WI L'EJO



AWOGBA Omode fun Girl, Eyi, Hiho-ahin, Orere. Ra Tire Ni Ile Egbogi — ISE — Olodumare Okebola, Ibadan. 116, Great Bridge St LAGOS

VOL. No. IX 508 ELETI-OFẸ LAGOS, SATURDAY, FEBRUARY 23, 1957. KỌBỌ MEJI (2d).

## Enmo re! Isu abami nilu Abakaliki

ABAKALIKI - Kose ro ni isu ti agbe kan wa jade ninu oko re, isu na je abami isu, o ni ori gegebi ti enia, o ni apa meji, o si ni ese meji. Bi o ba nwo isu na nibiti nwon gbe fiti ogiri ni iduro, laiseyemeji enikeni ti o ba ri, yio ni ero pe enia ni.

Okiki iṣu na kan nilu Abakaliki de'po ti Asoju wa ti ọrọ na ṣ'oju rẹ fi ya iṣu abami yi ni fọto, ki o ma ba si ẹrọ boya nibẹ, aworan iṣu na mbẹ nile iṣẹ Eleti-Ọfẹ fun ẹnikẹni lati yẹwo.

Ẹ wa wo iṣu abami ni 28, Kosọkọ Street, Lagos.

## Imale nfe isimi lojo Jimo

BIDA. Malam Abudu Salami ti o nṣe akọwe fun awọn ẹgbẹ Oṣiṣẹ P.W.D. nilu yi ti kọwe si Minisita ti o nṣe alabojuto fun ilẹ Bida wipe ki nwọn fi si igbimọ ni Kaduna pe ki ọjọ Jimọ jẹ isimi fun gbogbo ọmọ Imale, ki nwọn si ma fi gbogbo ọjọ Sat. ṣiṣẹ. Eyi yio fun ọmọ Imale laye lati sin Ọlọrun lọjọ Jimọ.

**THE NATIONAL BANK Of Nigeria Limited**

Incorporated in Nigeria in 1933
Paid up Capital – £1,130,000
Bankers to the Western Region Government of Nigeria.
HEAD OFFICE
37, MARINA, LAGOS, NIGERIA
22 Branches throughout Nigeria including
IBADAN, ABEOKUTA, IJEBU-ODE, OSHOGBO, OWO, ONDO, ILESHA, ILARO, BENIN-CITY, WARRI, SAPELE, ABA, KANO, ZARIA, JOS.
LONDON OFFICE
1 THROGMORTON AVENUE, E.C. 2.
Manager: F. O. Tyrrell
Telephone: London Wall 4303
Cables & Telegrams: Natbaniger, London.
Head Office Representative in London
Ernest Olubunmi Obasa—Porter
CORRESPONDENTS
NEW YORK PARIS HAMBURG

## Oba Ilorin yo Olofa kuro l'oye

ILORIN. Ọba Ilorin ti pe gbogbo awọn ọmọba ilu Ọffa jọ, o da ọjọ wipe, on fun wọn laye titi di ọjọ 15th oṣu March 1957 ki nwọn lọ ro o wo larin ara wọn, ẹniti nwọn ba ri wipe oye ọba tọ si, ki nwọn muwa siwaju on, nitoripe ọba Ọlọfa ti o mbẹ nibẹ nisisiyi on ko fẹ lori oye ọba mọ, nitorina ki nwọn tete fi ọrọ na si ero, ki nwọn mu esi wa fun on.



Inu ijọba Ilorin yio dun gidigidi si nyin bi ẹ ba le tete jigiri si ọrọ yi. Ki ẹ si ranti wipe, ẹniti o mọwe ti oju rẹ si la ni a fẹ lori oye ọba na.

Nigbati ọba Ilorin, Ọba Ọlọfa, Ajẹlẹ kekere, Balogun Ajikobi, Balogun Alanamu, Balogun Gambari ati Balogun Filani fi nṣọrọ lakọkọ, nwọn ko gba fun awọn ọmọba ilu Ọffa lati wọ'le a yafi nigbati nwọn pari ọrọ wọn tan ni Ọba Ilorin to wa pe wọn wọ'le, ti o si ba wọn sọrọ ti o wa loke yi.

Ṣugbọn awọn ọmọba ṣeleri fun Ọlọfa wipe, niwọn igbati ọba Ọlọfa ba si mbẹ laiye, awọn ko ni aniyan lati jẹ ọba miran nitoripe awọn ko ri ẹṣẹ ti ọba Ọlọfa ṣẹ, awọn ko si le mu kuro lori oye lainidi.

Ọrọ rogbodiyan yi ṣi nja ran-in nilẹ nisisiyi.

## Gomina Agba



Awcren yi ri ti Gomina-agba Sir James Robertson, ninu irin ajo re kakiri agbegbe Oshun, o gba iyi, o gba eye. Pelupelu nigba'i o de ilu Ogbomoso nibiti Oloye Akintoye ti gba a ni alejo.

A gbo pe awon egbe Scouts ati awon oluko ilewe na se eye tibi-tibi fun Gomina, agba nig ati o lo be ilewe U M S wo ni Igbeti, gbogbo wo na opa owo won soke, Gomina si gba abe re koja lo wo ile igbimo ibile ti ilu Ogbomoso

## Olopa Obinrin Fe Bere Ni Ibaban

Omidan A. G. Turnbull ti o nse olori Olopa fun awon olopa obinrin ti Eko, lo be ilu Ibadan wo, o si ba ogbeni A. N. M. Davies ti o nse Olori olopa Ibadan soro nipa dida egbe awon Olopa obinrin sile. Olori olopa o inrin na ye awon olomoge die wo, ninu awon ti o ti fi oruko sile o si seleri fun won lati pe won nigbati asiko na ba ya.

## Oba Ko Ngba Isimi F'oye Sile

OFFA. Irohin kan wi e Malam Abudu Kadiri ti o nse oba Ilorin ran eyinbo Ajele kekere si Kabiyesi Alaiyeluwa Isioye kini oba Olofa ilu Offa wipe, asiko to, ki o wa gba aye isimi, ki o fi oye oba sile ki nwon le fi elomiran s'ori oye. Nitorina ki oba Olofa ati awon igbimo re wa fi oju kan on ki awon jijo so asoye nipa oro na. Lese kanna, oba Olofa ati die ninu awon ijoye re si lo si Ilorin lati da oba lohun.

Nigbati nwon de afin oba Ilorin, ti nwon fi oro yi lo oba Olofa, a gbo wipe nse ni Olofa taku wipe, lati gba ti Yoruba ti nje oye oba, on ko gbo wipe oba kan simi ri, nse ni nwon nje oye na titi iku yio fi pa won on si ni ibi abajo miran ti on ko fi ni gba eyiti oba Ilorin wi yen. Nigbana ni oba Ilorin ni ki Olofa ma lo sile, bi o ba di ojo keji, ki on pelu awon omoba ilu Offa wa fi oju kan on.

Orisirisi iwe ni ijoba ile Oke Oya ti bere si gba larapa oro ti Olofa ti nwon so pe ayafi bi o ba gba isimi yi. Awon omo ilu Offa to nsise ni ilu Minna ti kowe si ijoba ile Hausa wipe niti wipe ki oba Olofa wa gba isimi, ofin na, ko be si, ki nwon yara pa ofin na re. Nitoripe, awon ara ilu Offa lo fi Olofa je, ko nse ijoba Ilorin lo fi Olofa joye.

Bakanna ni awon omo ilu Offa to mbe ni Ilorin ti kowe si ijoba Oke Oya wipe, ki nwon mase lowo ninu wipe ki nwon fi agbara yo oba won ti nwon nferan, nitoripe Ilorin ko nife ara Offa tele-tele.

Bi o ba je wipe nitori ogbo ni won se fe fun Olofa ni isimi Olofa na ko dagba to oba Ilorin. Nse ni oro na si nlo danin nile. Asoju egbe Afenifere to mbe ninu igbimo Assembly ni kaduna ti ko iwe nipa asa ati ofin ile Hausa lati fi ranse si Sardauna.

## Oba Adele keji ati Oba Elizabeth keji



Aworan ti a nwo yi ni, awon Alaiyeluwa Oba Adele Keji ti ilu Eko ati oba Elizabeth keji ti ilu Oyinbo, nwon fi egbe kan egbe nwon nki gbogbo enia. Akitoye ti o lo mu Oyiubo wa silu ko ko ni iru anfani ti oba Adele keji ni loni yi. A ko si gbo ri ninu itan wipe oba ilu Eko kan fi oju rinju pa pelu oba Oyinbo depo ibiti nwon o soro po, ayafi ni akoko ti oba Adele ni a koko gbo iru ra. Oloye Oluwo ti Makoli mu lo mo oba oyinbo, ti oba Adele ju eyi ni lo. O le die ni odun kan nisisiyi ti oba obinrin ilu oyinbo fi wa be ilu Eko wo. Ni odun 1925 ni H R H Prince of Wales wa be ilu Eko wo. Iyesi ejo na ko to ti Oba Obinrin.

# Obinrin kan fi omo re sile salo.

AKANRAN. Obinrin kan ti a npe ni Onimaka pe ọmọ rẹ obinrin ti ko ju ọdun meje lọ o ni ki o gbe apẹrẹ kalọ. Nigbati o de inu igbo o sọ ọmọ rẹ ti o ṣẹṣẹ bi kalẹ, o gbe le eyi agba lọwọ, o ni ki o ma tọju rẹ titi baba rẹ yio fi de. Ni Onimaka ba gba apẹrẹ lọwọ ọmọ rẹ agba, o si wọ igbo lọ.

Titi ilẹ nṣu lọ, Onimaka ko dẹhin. Ọkunrin a gbẹ kan ti o ni oko nitosi ibẹ ti o si ti ngbọ igbe ọmọ titun na, rọra yọlẹ wa wo ohun ti o ṣẹlẹ, o si ba ọmọde binrin kekere kan ti o gbe ọmọ ikoko dani. Agbẹ na bere pe, iya nyin da? Ọmọde na si dahun pe, iya on ni ki on gba, ki nma tọju rẹ titi ti baba on yio fi de, o si ti lọ lati oṅuro ko si ti pada de.

Ọkunrin agbẹ na tun bere nibo ni nwọn ti wa? O si dahun pe ni abule Ṣọmade ni. Agbẹ na ni ki o gbe ọmọ ikoko na pọn ki o niṣo nile. Nigbati nwọn dele, agbẹ na rohin gẹgẹbi ọrọ ti lọ. Latigbana wa, ẹn kan ko gburo Onimaka, ṣugbọn iya ọkọ Onimaka gba ọmọ na, o si tọju wọn titi eyi ọmọ agba fi wọle ọkọ, nigbati o ṣe ọmọ ikoko ti o fi silẹ ni ọmọ oṣu marun tun dagba, o wọ ile ọkọ o bimọ kini o bi ekeji, nigbati oyun ẹkẹta wa ninu rẹ, ni ọkọ rẹ pinnu lati ṣoyigi fun u.

Lọjọ ti nwọn nṣoyigi fun ni obinrin arugbo kan wọle de, o ni on ni Onimaka, ti o bi ọ. Emi! emi! ko nṣe emi lo bi nko mọ ọ ri, emi ni mo bi ọ, ti mo si fun ọ ni orukọ Mọlara.

Nigbati Mọlara gbọ bayi, o sare lọ rohin fun baba rẹ. Nigbati baba na de, o woju rẹ, o wo sura rẹ. o pe e Onimaka? O si dahun pe, emi niyi, ọkọ mi, ki loti rin? ni gbolohun ede ti o tun jade lẹnu ọkọ rẹ.

A fi aye silẹ fun ẹnyin ọkawe wa ti o ba le sọ ibiti obinrin yi gba lọ?. Nitori Baba ati Iya Onimaka papa a wa ni awati.

# Oko Oba Nlo Ba Iyawo Re

Ọrọ pala-pala, kati-kati, jagba-jagba ati rede-rede kan ti a gbọ lẹnu lọlọyi nipe awọn ni iwe irohin kan lati ilu Amẹrika lo sọ pe, Ọba obinrin ilu Oyinbo pẹlu ọkọ rẹ ṣẹ gbolohun asọ. Katikafi ni a ka iru ọrọ bayi si.

Lọwọ-lọwọ yi, a gbọ pe ọba obinrin na wa ni ilu Portugal ti o jẹ ilu nla kan ti awọn oyinbo Potogi leti ebute okun Bay of Biscay. Ọkọ rẹ si ti pari ajo rẹ kakiri agbaiye, yio lọ ba iyawo rẹ nilu na.

Njẹ bi o ba jẹ wipe lododo ni awọn oniwe irohin Amẹrika na sọ bawo lo ti ṣe nlọ ba iyawo rẹ lebu'e Portugal.

Ọrọ kati-kati, a ko gbọdọ gbọ mọ.


HINDU SANKARA'S

Religious Art Jewelleries



Perfumes, Charms, Mohammedan charms, Amulets, Vedic Prayers, Kawachas. Faithful Reproductions of Hindu Gods in the Jewelleries.

*Enclose 4/- money order by Air Mail for Catalogues and Literature.*

HINDU SANKARA, 20 Montpelier Row, Blackheath, London, S.E.3, England



*Family links with*

THE UNITED AFRICA COMPANY LIMITED

*Recording some of the many families who have found interesting, varied and worthwhile careers with the U.A.C.*



Chief Eruwa Okorodudu

Many years ago Chief Okorodudu, son of the Olu of Warri, took his family on a trading expedition to Burutu. There he founded the village that still bears the family name, the village of Okorodudu. In 1952, in honour of the Chief, a vessel of the Niger River (Transport) Fleet was named "Okorodudu", and his portrait can be seen on the ship's bridge. The ceremony was performed by the present head of the family, Chief Eruwa Okorodudu.

*Members of this family have served with The United Africa Company and its predecessors continuously since 1900. Their total length of service exceeds 160 years. The Company is proud of this unbroken link with so distinguished a family.*





The Okorodudu Family

The Record of Service of past and present members of the Okorodudu Family



Our pictures show some of the Okorodudu family working for the Company

# ELETI QFE

A-NJU-WQN KO SE WI L'EJQ
EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELGREAM
28, Kosoko Street, Lagos
P. O. Box 467
" ELETI - QFE LAGOS "
Phone 23370

VOL. IX. NO. 508. LAGOS, SATURDAY FEB, 23. 1957.


## Olola Dokita Nkrumah A Ba E Yo

Gẹgẹ'i irohin ti o gbojikan kakiri agbaiye nisisiyi wipe ilẹ Aganyin (Gold Coast) yio gba ijọba ominira ni ọjọ kẹfa oṣu March, ti ọdun 1957 yi, nilati jẹ iro idunnu fun gbogbo awa ọmọ Afrika, papaa awa ti iha'hin nilẹ Nigeria ti awa na nlepa ijọba ominira lọwọlọwọ yi.

A nilati fi inu didun wa ba Ọlọla Dokita. Nkrumah yọ fun aṣeyọri iṣẹ rẹ, fun ọpọlọpọ suru ati ifarada ti o fi gbe ijọba ilẹ Aganyin de aye nla ribiribi yi, nitoripe, ogun wahala kekere ko l'oja nipa oriṣiriṣi aro sọ ati abuso ọrọ ti awọn enia yio ti sọ si lara gẹgẹbi ẹniti o mu opo ijọba ilẹ wọn dani, Alakoso ijọba (Premier).

Gẹgebi o ye ti awa na nri lọdọ wa nihin fun oniruru aro sọ ọrọ ti awọn miran nsọ si Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ, lori gbogbo wahala rẹ lori wa, ki a le bọ ajaga na silẹ, sibẹ ti ko sinmi, ti ko si baye lati mu awa na de oritẹ-ogo, ti a npe ni ijọba ominira, ti a ngb'orun rẹ ni ẹhinkule ile wa nisisiyi.

Nitorina, bi a ti mba Dokita Nkrumah yọ fun aṣeyọri iṣẹ rẹ, bakanna ni a si nkan sara-iyin si Oloye Ọbafẹmi Awolowo, Alakoso ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun nilẹ Nigeria ti o nṣe iṣẹ ribiribi lati mu awa na gba ominira.

Ki ẹgbẹ Afẹnifẹre o pẹ, ki ẹmi Oloye Awolọwọ gun pẹlu alafia fun agbega ogo ilu wa.

## Olobinrin Pupo Ni Mo Fara Mo

Oletu,

Gba mi laye lati dahun si ibere Dokita Jẹnmi, ti o jade ninu Eleti Ọfẹ. Idahun temi ni pe, Iyawo kan ko to fun ọkunrin kan, bẹ si ni iyawo mẹrindilogun ti pọju fun ọkunrin kan,

Eyiti Ọlọrun paapa fẹ ti o si faṣẹ si, ni obinrin mẹrin, eyini na si to fun ọmọluwabi obinrin pupọ ni mo fi ara mọ.

Y.A. Braimoh
Ara Eko






## Ejo Kan Lasisi Oluwa

Lẹhin ti ẹṣu ti lọ de Ogundipẹ mọ inu ina tan, o tun pada wa ba Lasisi Oluwa, o ni to! iwọ ọrẹ mi ewo lo ri sọ si ọrọ ti o delẹ yi?

L. Olu - ṣe iwọ Olotu wa mọ wipe, ọmọ awo ni emi nṣe, ọmọ awo ko si mba awo jẹ. Bi o ba kan ọrọ ti ilẹ yio ti ku, nṣe ni ilẹ yio ṣa

Eṣu - Ṣe o mọ wipe ki Apalara to di alufa, o ṣe awo, o ṣe Oṣugbo.

L. Olu - Bẹni kẹ! ọmọ abe mi lo nṣe nigbana, gbogbo wa lo si njẹ apadari ninu ile Irẹlẹ.

Eṣu - Ẹniti ejijọ ti nṣe awo ri, ti ẹri pe ko si tun ba nyin ṣe awo mọ, eṣe ti ẹ ko fi wadi ohun ti o fa a ki o to tun ṣawo-ṣọgberi?

L. Olu - Ko sọ fun wa pe, on ko ṣawo mọ, nigba gbogbo to ba ri mi lo ma ndaro si mi bayi pe "Ẹṣin kere, ẹṣin tobi" emi a si ma dalohun bayi pe, "Ọtọtọ enia, ni yio ṣe Onigbọwọ ẹṣin" ko si sọ pe on ti tu nba, boya a le ri ẹniti yio tunba gegebi tirẹ.

Eṣu - Iwọ ko ha gbọ owe ti awọn enia npa wipe, ọrọ diẹ to fun Ọmọluwabi. Nigbati ko ba nyin pejọ mọ ti o ntu aṣiri nyin, eyi ko ha to fun nyin lati fura pe o ti tu nba, o si ti ya kuro lọdọ mi?

L. Olu - Ori inu wa ti yio ba ti ode jẹ ko jẹki a fura, lọjọ ti mo lọ sile Apalara, ti a jijọ sọrọ kan, ti inu wa dun Apalara lo kọkọ gbe orin yi wipe "Aid'ode, k'a ma k'Olode", mo si fi ohun awo da lohun wipe "Ode Gbamgba, ero oja gbamgba" Iru iwa bayi ko jẹki a ronu wo.

Eṣu - Paapa gidi, kini Alufa Apalara ṣe ti o fi dibinu fun ọ?

L. Olu - Oro ti o nṣe nişoju obinrin lo mbi mi ninu, bi baba mi ba dan iru ti Apalara wo, nilu Eko yi, Oro na ni yio gbe oluwa rẹ.

Eṣu - Njẹ ninu ẹnyin pẹlu Apalara, tani Oro gbe ju ekeji lọ?

L. Okete ni ti ọrọ ba de ibi iru ki a fo, ati Oro ati Agẹmo, awa enia mọkanla l'o fori fa gbogbo rẹ.

ẸJỌ RIRO KAN KOSEGBE

Lẹhin ti Eṣu ti lọ de Lasisi Oluwa mọ isalẹ ina ọrun apadi tan, o tun pada wa fa Koṣegbe jade, o ni ẹjọ kan ọ o si bẹrẹ si ki i mẹsan, mẹwa bayi wipe, Kai, ọkunrin Ogun o g'ẹfọn re ibi ija, agbeti niti Ọmọri-Odo agbeti Nihin ni ori Koṣegbe wa wule, o si daria bayi wipe

Koṣegbe - Gir-r-rigbo, gidigbo!

Eṣu - Heya!

Koṣegbe - Magbe - magbe, o wiwo m gbe-magbe o wuwo o ẹru mi ma pọ, o wuro.

Eṣu - Ṣugbọn ohun ti ko ba ṣe gbe, O ni lati ṣe wọ, tabi nigbati awọn enia gbe ọ ni agbeti, njẹ Apalara ko ha wọ ọ kuru?

Koṣegbe - Kini njẹ be! wiwọ na pọ. Boba jẹ mo mo pe, ohun ti Apalara yio fi mi ṣe nijyi ni, ṣe iwọ eṣu paapa mọ pe ọmọ agan ni emi nṣe, mba, ti fi agan gbe nigbogbo asiko ti o fi ntu aṣiri wa ni Mush o.

Eṣu - Mo ṣe bi ọrẹ ni iwọ pẹlu alufa Apalara, njẹ iwọ ko ha dalẹ ọrẹ, ki o to di ohun ti ilẹ Ọgẹrẹ fi mu ọ bẹ?

Ogun Ọrun - Ogborilẹ o jẹku o, o gbori ilẹ o jẹja, o gborilẹ ẹkun aṣeke ṣe ranti ilẹ ti ẹ jẹ mu

Koṣegbe - Ẹ panu nyin mọ tabi ẹnyin ko mọ pe ijoye ni emi jẹ ninu Awo Ọpa, emi ni riwo-riwo ya! mo le bawo jẹ mo si le tun Awo se.

Eṣu - Njẹ oju nyin ko ha nri ohun ti oju ẹnikan ko riri bayi?

Koṣegbe - Jọwọ, mi tun sọ nipa eyini mọ, a ti ṣe abosi fun ori ara wa Oṣe! a ko mọ pe bayi ni igbẹhin aiye wa yio ri.

Eṣu - Oṣe lo nṣiwaju ẹkun, abamọ lo si ngbẹhin ọrọ, gbogbo ọtọkun ilu pejọ, nwọn ko ri ogun abamọ ṣe. Oju ti nyin loni, Bakanna ni ngo gun ọ lẹsin wọ ọrun apadi ninu ọgbin ina ainisalẹ.

## Abahun Ajapa

JOS. Ibi gbogbo ni Ajapa wa, ajapa mbe ninu Okun, eyiti a npe ni ahun-Okun, o mbe ninu osa ti a npe ni ajapa osa, o mbe ninu igbo eyiti a npe ni Ahun, o mbe ninu ira ti a npe ni Ewi, ajapa si tun mbe ninu asale. A gbo lenu awon agbagba wipe, bi ko ba si dasi, ajapa miran a ma gbe to egberun odun laiye ki o to ku.

Laipe yi ni oba Kasina fi ajapa kan ti o ti mbe ninu afin oba Kasina lati iwon adota lerugba odun sehin ta olotu ile ibiti a nse itoju awon eranko lore ni ilu Jos. Ajapa mejeji na je tako-tabo eyi ako tobi to 64lbs, abo si tobi to 72lbs,

# Kilo fa ogun Oyinbo ba Ilorin?

Awọn opitan sọ fun wa wipe, awọn Gẹsi ko dede gbogun si awọn ara Ilọrin, ohun ti o fa a ni wipe, awọn Ilọrin nlo anfani ti wipe, nwọn ni awọn enia pupọ lẹhin nwọn a si ma fi eyi boju gbe suamọni kakiri lati ba ri ẹru pupọ ko. Awọn Gẹsi ti ni mimọ eyiyi tẹlẹ. Nitorina nigbati nwọn nlọ si Ilọrin, nwọn ti mura, pẹlu ti buruku ati ire. Ṣugbọn nigbati Ilọrin fiji lọ wọn ni ọdun 1897, nwọn kuku gba lati fi oju ọkunrin meji ri ara wọn.

Irohin ti tan kakiri nilẹ Tapa ati Hausa, iru iṣẹ ti Gẹsi ṣe ni Ilọrin, nitorina, awọn ara ilẹ Kotongora ati awọn ara ile Bida ti bẹrẹ si gba ogunjọ silẹ de awọn Gẹsi. Awọn Ṣọja to lọ ja ogun Ilọrin wa lọ tẹdo si afonifoji odo Kaduna ni agbegbe ile Kotongora ibẹ ni awọn ara Kotongora ti yọ kẹlẹ-kẹlẹ lọ bo awọn ṣọja na mọlẹ, ṣugbọn Gẹsi le wọn pada sẹhin. Awọn Gẹsi ranṣẹ si Eko, ki nwọn fi ṣọja ranṣẹ si wọn.

Nigbati o di ibẹrẹ ọdun 1901 ni ogun awọn Folọntia de (Volunteer). Ni gbogbo asiko igba wọnni, ọkunrin Fulani kan ti nwọn npe ni Malam Jubrila ti n wọn npe ni Olugbala eniti o ko ogun ola wa fi sumọmi ja awọn ṣọja logun ni afonifoji odo Kaduna wa bẹrẹ si ko ogun jọ, o tun nieri de awọn Gẹsi. Nigbati ogun Gẹsi de, o fẹ salọ ṣugbọn ọwọ Gẹsi tẹ, ninu ewọn lo ku si. Lati gba na wa ni ijoba Gẹsi ti bẹrẹ nilẹ Tapa ti ko si ogun mọ, ti ọtẹ si buṣe.

Irohun tun de ọdọ Gẹsi wipe ọba Yola ati ọba ilu Bauchi jẹ ogbologbo oniṣowo ẹru, nitorna, nigbati awọn Folọntia kuro nile Kontogora nigbati o di inu oṣu Sep, 1901 nwọn de ilu Yola, nwọn fi ija lọ wọn, nwọn si ṣẹgun, ṣugbọn ọba ilu na sa kuro loju ija, o si salọ bamubamu. Nwọn fi idi ijoba Gẹsi lelẹ, nwọn si fi ọmọ ọba na jẹ oye sori itẹ baba rẹ.

Nigbati ogun si wa ni Kotongora lẹhin ti Gẹsi ti ṣẹgun tan, ọgagun ran awọn ikọ si ọba Kano wipe, awọn ti ba ilu Kotongora ja, ọba ilu na si salọ ki nwọn yan ọba miran wa sori oye, ọba Kano gba iwe na, ṣugbọn ko fesi. Nwọn si tun ran oniṣẹ si ọba Ṣokoto, wipe, ki ọba na fun wọn lesi kia-kia, iru iku wo lo pa Captain Moloney. On na pẹlu ko fesi.

Nitorina nigbati Sir Fredrick Lugard nlọ ba awọn ilu mejeji nwọnyi lẹhin ogun Yola ati Bauchi o gba ogun nla jọ nitoripe, o ti gbọ pe awọn ilu mejeji na tobi. Ẹgbẹrun Folọntia lo ko dani lo ba wọn ni ọdun 1903, o fi ja lọ wọn, o si ṣẹgun wọn.

Bayi ni ilu Ṣokoto ati Kano di ti Gẹsi lati ibẹrẹ ọdun 1903.

# Ijoba Ibile Ko Ilewe Titun

ILỌRIN. Awọn ẹgbẹ Oke-iya ti ijọba ibilẹ kọ ilewe titun kan si Oke-iya lati ma kọ tọmọde-tagba ni ẹkọ iwe bi a ti ṣe nka ati bi a ti ṣe ẹkọ fun awọn Alakọbẹrẹ.

Oba Ilọrin Malam Abdul-Kadiri pẹlu Oloye Yahaya Ilọrin Maida akiti lo lo ṣi ilewe na fun ijoba ibile. Yahaya so fun gbogbo awọn ti o wa si bi iṣilewe na wipe, ki awọn ara Oke-iya maṣe jafara lati ran awọn ọmọ wọn lọ si ile ẹkọ yi nitori owe Yoruba kan sọ pe, ti o ba ngbọ gbe, gbe, gbe, ẹ ti o ko ba tete ba wọn gbe, ẹhinkule oluwa rẹ ni nwọn o gbe ju si.

Gbogbo agbaiye lo ngb'ẹsẹ siwaju fun ilọsiwaju nilu wọn. Ko si nṣe wipe nitori ti nwọn ti ko ilewe kan fun awọn alakọbẹrẹ ki nwọn lọ simi ṣugbọn ki nwọn tun mura ki nwọn tun le kọ ilewe giga ki o maṣe jẹ wipe ilu miran ni ao ma ran awọn ọmọ wa lọ kọ ẹkọ iwe giga. Ijoba Ilọrin yio si ma fi oju si gẹgẹbi iṣẹ ilewe na ti nlọ si.

Alhadji Adeyẹye ni yio jẹ olukọ agba nilewe na.


## Kere o!

A ti ni oriṣiriṣi ogun Germany to ṣẹṣẹ de, fun oniruru aisan ọkunrin tobinrin. Tete wa ra tirẹ k'o to tan.

**J. A. AJAO BROTHERS**
MEDICINE STORES
7. Egerton Road, Lagos


## OGBENI E. S. IKOLI



Ogbeni alagba ti a nwo aworan re yi, ni Ogbeni E. S. Ikoli, ti o je okan pataki ninu awon olotu (Editors) fun awon iwe irohin bi Daily Telegraph, ati Daily Times nigba aiye atijo ati lasiko ote Gbegi ati Gbebo, ati nigbimo asofin (Legislative Council) ati ni igbimo Munisipa, nisisiyi ko tun se ise Olotu Iwe irohin (Editor) mo, awon omo kekeke lo ku lenu re.


BICYCLE

**Ra Siga Basikulu eyiti o lokiki nile Nigeria**



## Awon to lu Loya pa jebi apania.

Lasiko kan l'a gbọ iroyin wipe Lọya kan rlọ si ọna oko fun iṣẹ lọna Onitsha, lairo tẹlẹ ni mọto Lọya na ṣeṣi pa ara abule kan. Nṣe ni awon ara abule na tutọ soke ti nwọn si fi oju gba a nwọn ni (Do me, I do you, God not de fex) eyiti a le tunmọ si bayi wipe "Ẹdiẹ da mi l'ogun nu mo si fọ l'ẹyin".

Awọn ara abule na rope ika ni lọya na fi ṣe a fun, a forun, a ya fi bi nwọn ba lu Lọya na pa dipo enia won ti mọto pa. Nigbati Lọya na ri oye pe nṣe ni nwọn fẹ pa on nitotọ, o sare wọ ile Padi lọ, o si lọ di mọ padi lẹsẹ.

Nṣe ni awọn enia na rọ giri de pẹlu kumọ ati ada nwọn ni ki alufa Padi ti i s'ode fun wọn kia-kia, bi bẹkọ Padi yio fi ori ara rẹ fa ẹjẹ ra. Nigbati Padi bẹ bẹ titi ti nwọn ko gba, Padi ti gbogbo enia ilu na ti mbọwọ fun, ti nwọn si nke, o di ohun ti nwọn nyan ebu si lara, lo ba fi le wọn lọwọ. Agbaregbano, nwọn lu Lọya na pa.

Ọ ọ na wa di ti ọlọpa enia mẹrin la ni nwọn ka ẹsun apania na mọ lẹsẹ niwaju adajọ kekere, adajọ da enia mẹsan silẹ, o wa gbe awọn si Asaisi. Adajọ Asaisi sọ pe awọn mararun jẹbi apania, ki a lọ yẹgi fun wọn. Nwọn sọ pe ẹjọ na ko tẹ wọn lọrun nwọn gbe lọ si ẹjọ kotẹrun, nwọn tun da wọn lẹbi iku, ọkunrin mẹta, ati obinrin meji.

## Idahun Si Ibere

Olotu,

Nipa ibere ti o jade ninu iwe rẹ wipe bawo ni a ti ṣe le na ọkẹ kan Pọun tan lọjọ kan ti a ko ni ra orisi nkan meji papọ.

Awọn enia ti o ti nfesi si ibere na lati ọjọ yi wa, ko fesi dara-dara. Awọn ẹlomiran ni, nwọn o fi g'ogbọ owo na ri ile, ẹlomiran ri on yio ra mọto. Mo fẹ ki o ye awọn enia na wipe, eniti o nfẹ ra ile ko le ri iru ile ti o fẹ ra lọjọ kan, bẹni ọjọ kanṣoṣo ni nwọn fẹ ki a ti na owo na. Ẹwẹ, ẹniti o nfẹ ra mọto, ko nṣe lọjọ ti o kowo de bẹ ri nwọn o gbe mọto fun.

Niti emi, bi nwọn ba gbe £20,000 fun mi pe ki nna tan lọjọ kan, nṣe ni ngo ko gbogbo rẹ lọ da si inu Banki

Emi ni
Emilius Adekẹyẹ
Ara Eko

ẸNITI O KỌWE YI KOITI MỌ OWO NA

Ẹniti o fun ọ ni owo yi, ko sọ wipe ki o fi pamọ nṣe lo wipe ki o na gbogbo rẹ tan pata-pata, ko mase ku edolo. Eyi fi han wipe iwọ alaia pa pa koiti mọ owo ni ina kini o ma ko pamọ si?. O nfe ki o sọ nkan ti iwọ yio fi ra ati iye ti o ra a ki gbogbo rẹ ku si £20000

Ẹṣọ

## Ede E ku Aro E jire

Olotu,

Mo fi iwe yi ṣe alaye diẹ lori akọle ti mo ri ninu Eleti ọfẹ wipe "Adun wa ninu ede Yoruba" eyiti o jade l'ọjọ Abamẹta ti o koja lọ yi.

Mo fẹ lati mu otitọ na wa si gbamgba bayi pe "Yoruba l'ede adajye-ba" ede na ko si parẹ ri ati Ile-Ifẹ Ọyẹ-ilu-agbo ko parẹ nigbati gbogbo aiye fi parẹ. Ọgbara, ṣẹlẹru ati ikunomi wọ Ile-ifẹ o wole, o si gba ọpọ awọn enia lọ.

Ọpọ enia le salọ kuro ni Ifẹ. Ṣugbọn nigbati omi fa, nwọn tun pada de. Awọn agba Arọkin lo pitan na.

Fulani daran-daran ni baba nla awọn Heberu ati Larubawa. Ko si ti bimọ rara nigbati o ṣe atipo wọ ilẹ Egypt. Ọgbọnlẹsiriawo ede ni Egypt ti nsọ ki baba wọn to de. Egypt paapa ṣe lati ilẹ ku arọ, ẹ jire.

A nkọ iwe itan ku arọ, ẹ jire lọwọ ao si pari rẹ laipẹ lagbara Ọrunmila Ọṣẹṣe igbo.

Ijọ Ọrunmi Adulawọ

## Ile ejo ibile yio gba awon Agbejoro laye

Okan ninu awon iwe eto ofin titun ti yio jade si ile igbimo asofin (House of Assembly) niti ofin atunse lori Kotu ibile ti nwon nse gegebi asiko ti a wa nisisiyi pelu awon eto iselu ti ode oni.



OLOYE ROTIMI WILLIAMS

Awon Kotu ibile ti o ti wa tele yio pin si orisi merin, A. B. C. ati D. eyiti yio gbaye fun awon amofin agbejoro (Lawyers) ni Kotu ti Grade 'A' awon Kotu orisi meteta yoku ko ni gba Loya laye.

Gbogbo ayipada rere wonyi nyoju s'ode lati owo Oloye Rotimi Williams ti ise Olotu awon ile ejo ti ijoba ibile ni Iwo-orun.

## Iyawo Mbu So Oko Loruko

Nibiti nwọn nṣe iṣẹ ọkọ oyinbo kikan nilu Scotland, ibẹ ni nwọn ti kan ọkọ oyinbo kan, eyiti Ọlọla Gomina agba yio ma wọ lọ lati lọ bẹ awọn ilu kekeke ti o mbẹ leti ọsa wọ.

Ọkọ na gun ti ẹsẹ ma rundinlogoje, agba ibon meji si wa ninu rẹ lati ma fi ṣe ikede wipe Gomina de. Iyafin Mbu lo sọ ọkọ na ni orukọ Valiant, on lo si ṣe etutu ti nwọn fi fa ọkọ na sinu omi, ọkọ na funra rẹ ni yio rin lati ilu ọba wa si Eko.

## Sports Meeting

The Fifth Western District Annual Sport Meeting of the Railway Amateur Athletic Club will be held at the Railway Sports Ground, Ebute Metta, on Saturday, 23rd Februry, 1957.

Competition starts at 4 p. m. and athletes are expected to attend fromHeadquarters (Ebute Metta), Abeokuta Ibadan, Ọffa, Ilọrin and Jebba.

IMORAN FUN ENYIN ABIYAMO

Enyin abiyamọ ewa ra ỌMORELA o dara pupọ fun awọn ọmọde.

Ama je ki omode ri orun sun daradara o dara fun otutu, ikọ ati orisirisi arun miran ti o ma mba omode ja ni asiko ehin. Opolopo abiyamo lo ti lo egbogi yi fun omo won ti won si so wipe odara pupo fun awon omode

ỌMORELA BABY MIXTURE
(SILE MEJI ABO 2/6d. FUN GO KAN)
O wa lọdọ:—
COMMERCIAL MEDICINE STORES
(Qualified Chemist)
10, VICTORIA STREET, LAGOS

## Iwora

Nigbati ara enia ba nfẹ gan Ohun ti o nfa ni wipe nigbati Kidinrin enia koba ṣiṣẹ daradara arun iwora yi ni ikilọ fun oluwa rẹ lati mọ wipe Kidinrin ko ṣiṣẹ to nitorina ewu mbọ ti enia ba nlo egbogi yi yio ri alafia.



Ohun pataki ti o fa amodi wa fun enia ni wipe idọti pọ ninu ẹjẹ oluwa rẹ, lọ dan egbogi De Witt wo fun ra rẹ o le jẹ ohun ti o nfẹ lọ ra ọkan wo ninu ṣọbu egbogi.

DE WITT'S PILLS
for Kidney and Bladder Troubles


# Azikiwe Nilati Po Owo To Ti Je

LONDON. Igbimọ ti nwọn ṣe nilu Oyinbo lori Dokita Azikewi wipe, owo ti Dokita Azikiwe gba ni Afrikan Continental Bank gẹgẹbi owo iṣẹ Olotu Ban-



DỌKITA AZIKIWE

ki na, gbogbo owo na jẹ £5,252 ki o yara da owo na pada kiakia si Continental Bank. Gbogbo ipin ti o ni ninu banki na, kio da pada, fun ijọba Ila-Ọrun laini ere ninu rẹ.

Nwọn tun here ninu igbimọ wipe, nisisiyi, kini ero ti ijọba gba nipa iwadi ti ijọba ṣe nipa ọrọ ọkunrin na, ijọba na si fesi dahun pe, Gomina Ila-Orun ti ranṣẹ sọ wipe Dokita Azikiwe ti gba lati da gbogbo owo ti o je ninu banki na pada gẹgẹbi gbe'e ti on ti jẹ ninu banki na ko si ni si owo kan ti ao da pada fun.

Pẹlupẹlu ijọba si tun nroo lọwọlọwọ bi o ba tọ ki ijọba Ila-Orun ni ẹtọ lori owo ti nwọn fi pilẹṣẹ banki na, (Capital) lori eyi ni ọrọ na dikoko nipa ofin ati eto ṣiṣẹ gbe ku si ero lati pari.

## Eleti Ofe Gbalejo

Gbuke ni awọn alejo meji kan lati Oke - Okun yọ si ile iṣẹ Eleti Ofẹ, nwọn si fi ara wọn han wipe nwọn jẹ ọkawe iwe irohin Eleti-Ofẹ, nilu Abonso, orukọ wọn ni, Ọgbẹni Raji Ade Bello, ti o nṣe ọmọ Ile Afungbaoge, nisalẹ Ọra, Ogbomọṣọ. Ẹnikeji ni Shehu Tijani, ọmọ ile Alufa Mustafa, nisale Ọra, ni Ogbomọṣọ.

Awọn alejo mejeji na jẹ ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre, nwọn si jẹ ijoye ninu ẹgbẹ na. Nwọn wa si Eko lati wa ra ọja nitoripe onișowo ni wọn, nwọn si ti pada si ẹnu iṣẹ wọn. Ọkọ Ofurufu ni nwọn wọ wa, nwọn si ti ba ọkọ ofurufu pa a si ẹnu iṣẹ wọn.

Nwọn ba Ẹṣọ Ikoyi nile, nwọn si fi ọrẹ ye ara wọn, nwọn No-Polo ṣugbọn ko si Lemọmu Ajakuta nile. O dabọ o, Ọkọ a refo o, ori Oduduwa yio gbe yin.

Awọn gbajumọ mejeji na jẹ abiyi enia, nwọn ti jẹ ọbẹ nilẹ Aganyin, nwọn si ti yọkun, nṣe loju wọn tutu minimini.

## Onido ti Iddo osun wo aja

Nṣe ni gbogbo enia njo mukumukẹ pẹlu ohun orin bayi wipe, "Ile lo lọ tarara, baba rele o, ile lo lọ tarara." Nigbati a ṣe abere ẹhin wo wipe tani ku, nwọn ni Ọba Onido ti ilu Iddo Ọshun lo ṣalaisi nigbati o dagba di ẹni ọdun mejile-logọrun (102 years).

Awọn ero pọ nibi oku na to ẹgbẹta enia. Ẹhin oku na yio dara, awọn ọmọloku fẹrẹ to ọgbọn ninu ọmọ, ọmọ-ọmọ, ati ọmọ-ọmọ-ọmọ.

# Idahun si Ibere Dokita Jenmi

OLOTU,

Jọwọ gba mi laye ninu iwe irohin rẹ oloyinmọmọ lati dahun si ibere Dokita Jenmi, ti o bere wipe, ninu olobinrin kan ati olobinrin pupọ ewo lo dara?

Idahun temi niyi, Olobinrin pupọ lo dara nitoripe nigbati nwọn ṣe iṣiro gbogbo enia ti o mbẹ nilẹ Nigeria, awọn sọ pe awọn obinrin jẹ ilọpo mẹrindilogun si ti ọkunrin. Bi o ba jẹ wipe ki ọkunrin kọkan ma ni obinrin kọkan, tani ki o fẹ awọn yoku? tabi bi ọmọ tirẹ ba jẹ obinrin nkọ, nibo ni ki o ti ri ọkọ fẹ?.

Nitorina emi ko fi ara mọ olobinrin kan.

Emi ni,
Aminu Sorry

## Esi idahun Ogbeni J. A. Afolayan

IDAHUN RẸ KOTỌ SUNA

Adupẹ jọjọ fun ẹniti o mu idahun oke yi wa, idi rẹ ti a ṣe wipe idahun rẹ ko tọ suna ni wipe nje Ọgbẹni Afolayan le juwe ile kan fun wa ti o jẹ wipe nwọn nfẹ ta ni £20,000 nisisiyi. Nitorina, ododo ni a fẹ ki ẹnikẹni sọ ko nṣe abuṣọ.

Ọmọ Ẹṣọ

# Salako Ko Omo Re Jade

Ọgbẹni S. Salakọ Balẹ Ọkọ ilu, ni Ọlọrun fi ọmọ kunrin rubutu kan ta lọrẹ lati ọdọ iyawo rẹ Simbiatu enia pọ jọjọ nibi ikomọ na, awọn alufa Alhadji Sanmọri lo kun ibẹ Alhaji Ajaṣẹ lo ke wutuba le ọmọ na lori, o si fun ọmọ na ni orukọ yi Suraju-deen.

Baba ikoko fi jijẹ ati mimu tẹ enia lọrun. Diẹ ninu awọn gbajumọ ti o wa nibi aṣe ọmọ yi ni Ọgbẹni Y.A Jolaoso - Olori S. Salakọ Balẹ, L. Bello, Alakoso, S. Akinọla-Balogun, Akanbi Magnus-Ọtun, I. Showa'e-Osi Ade Akanbi - Ẹkẹrin, A. O. Mọgaji - asst Sec, T. Salami Finer, Shosanya Ajirọba, M. Oluṣesi-Alufa, S. Ogunmuyiwa - Arẹ, A. Oduṣina ati Fatusi.

# India nfe ba ara won jagun.

Irohin kan wa lara lati ilẹ Amẹrika wa wipe awọn apakan ninu awọn ẹya ilẹ India ti a npe ni Pakistan ngba awọn ọmọ ogun jọ lati fi ba awọn ara ilẹ India yoku ja tabi boya awọn ẹlomiran ni nwọn yio ba ja.

Awọn ti a npe ni Pakistan yi jẹ Imale, awọn yoku jẹ aborisa, nwọn si nsọ fun awọn ọmọ ogun Pakistan na wipe, Ogun mimọ ni nwọn nfẹ ja yi. (ogun Ẹsin ni nwọn npe ni Ogun mimọ).

Ṣugbọn Ọgbẹni V. K. Krishina Menon ti o nṣe Minister fun awọn ilẹ India sọ wipe, asọtẹlẹ lo njẹ ọrọ ana, nitotọ ni on roye wipe awọn ijọba Pakistan ngba awọn ọmọ ogun jọ bi nwọn ba kọlu ilẹ India awọn yio nilati dabo bo ilu tiwọn nitoripe, koji, ko wi, koni wipe ki Olobun ma lọ ohun rẹ.

## Danasungbo Sun Ilu Kan

A gbọ irohin wipe ogidinlọ jẹ ile ti o mbẹ nilu Orlu nilẹ Ibo jẹ ile korko, o si wa fiditi igbo. Awọn agbẹ lo dana si papa, ti ina na jo titi o fi ran awọn ile koriko ti o mbẹ leti igbo ki nwọn to parada, iwọn ọgọrun ile ti gbina ofo ati ẹdanu ti o ṣẹlẹ nibẹ fẹrẹ to ogoje Poun.

**E ma ka iwe irohin Eleti Ofe ki e si ma polowo oja yin sinu re.**

# Oloye E. A. Fadayiro



Aworan inu iwe wa yi niti Oloye E. A. Fadairo Apesin Ilero, ni odun 1952 ti o si tun je oye Olori Apesin Ilero ninu odun 1953. Ninu odun 1956 ni a yan si igbimo Asofin ti Ijoba Iwo-orun, on ni nwon gbe si ipo Minista kekere fun Alabojuto e'o. (Minister of Home Affairs)

Ola nsubu lu ola, oye nsubu lu oye – iyen wun wa o, Apesin tiwa.

## L E D B
# Enia Kika Bere L'oni

Lejo Satrday oni yi, 23 2. 57 ni awon akowe bere si ya ojule lati ma ka awon enia kakiri ni agbegbe Idi-Oro ati Suru Lere, nitori ki won mo bi enia ti po si, lati le tun agbegde ibe se.

Ero asoro magbesi yio ma so lorekore gegebi awon enia ti nwon ka na ti po to.

Awon L. E. D. B. ti nwon fun lase lati se eto ati ilana ilu Eko ti bere ise won, pipo enia ni nwon o ma wo fi sise na gegebi o ti to ki o dara to.

# Soja pa Amotekun

KADUNA A gbo irohin wipe Koburu Dickson t. o je okan ninu awon soja gbe ibon dani, o nwa okun kakiri inu igbo. Bi o ti nwa okun yi kiri, samosamo amotekun kan ti gborun re, o si nlepa re bowa.

Ki ekun na tori Soja yi, Soja tiri ekun o duro, o si fun ekun na ni owo meji (2rds) fifo ti ekun na fo, nse lo gbe ara sanle, ti o si ku bamu-bamu.

E polowo oja yin sinu iwe irohin Eleti Ofe

# U.A.C. Fe Fi Bicycle Dara

EKO Ogbeni Reg. Harris eniti o gba oye asiwaju ninu ere Basikulu yio de si ilu yi ni owuro ojo Monday ojo 25th February 1957, ni agogo mesan abo 9.30 a.m

Bi o ba di osan ojo na, yio fi Basikulu Rali dara lati eda titi de ebute Ebingbetl ni ile ise Miller Bros. Ni ojo keji Tuesday 26th February 1957. Oba Adele II yio pin ebun orire fun awon eniti o ba ie ninu orire ti ao fi Basikulu ti Ogbeni na ba gun ta

E mase gbagbe! enikeni ti o ba de odo re yio gba Kadi nile itaja Rali Basikulu ni 49, Marina l'Eko

# Alao O! alo

1. Ojiji fi-i, arogba aso ma ba le, kilo nje be ?
2. Eyin rubu, e y i n rubu, olorisa ki se ki o to je kilo nje be ?
3. Igbo kan ko gba Erin, Aleju ko gba Efon, aleju gbe enia mi tisbotigbo. kilo nje be ?
Enikeni ti o ba mo alo yi ki o kowe si

J. A. Afolayan
53 Tapa St. E. B.

# Awon Janduku Gb'ogun Ti Egbe Afenifere Nile Ibo



Oloye Tony Enahoro ti e nwo aworan re yi ni awon janduku ile Ibo, nilu Portharcourt da oko bo Moto re nibi ipade ti awon egbe Afenifere (Action Group) se fun ikede ibo (Campaign) ti nwon je di nile ibo fun igbimo ijoba Ila-Orun.

Eyi fihan gedegbe wipe omoluwabi s'owon ninu awon egbe Kobokayi wonyi, ohun ijongbon ki won ni sakani won.

"Ambitious people prepare for bigger incomes. The English Association of Accountants and Auditors. The English Association of Estate Agents and Valuers. The English Association of Secretaries. Founded 1941. Membership by exemption (state professional experience) or Examination with Coaching by Correspondence College. Founded 1885. 9, Charles St., Newport, Mon. England".


# AWO REKODU 6/-

Wa ra awon rekodu ti o gbadun nwonyi lodo wa:

1870. E s i o r o nyin ; Lawani Akano – S. Aka
1871. Omo atiro ; Olanrewaju — „
1872. Abanije ; Bisiriyu Kayode — „
1876. Late Awoyele ; Daniel Oreyomi – Ayinde Bakare.
1877. Late Omosola Savage ; Ore meji — „ „
1878. L.O. Gbamgbala ; Sule Mayeto — „ „
1884. A j o m o g b e . Moronmubo – Rio Lindo
1885. Late Omosola ; Jo Mambo — „ „
1886. Olomo lo laiye ; Late Awoyele — „ „
1887. Sio lele ; Late Chief Thomas — „ „
1902. Ogede Mbaje ; Eda ma tori awa da – Alabi Ewuro
1903. Igba mbajo ; Eleko Adisa. — „ „
1904. Gbi ni mo gbo ; Erjumi lokun — „ „
1912. Aka se mi lalejo ; Jubirila – Lamidi Ajeigbe
1913. Af'emi - af'emi ; Mo re mo kan — „ „
1914. Ma mowo ra ; Kinkin n i mi — „ „
1915. Oba ile a i y e ; Mapaja — — „ „

Fi owo - o k o kun o w o oja ti o ba fe r a.

**Egba Trading Aradan Stores**
18, Denton Bridge Street,
P.O. Box 2, Ebutte Metta.


Printed & Published by The Union Printing and Publishing Company, 28, kosoko Street P. O. Box 467 Lagos Phone 23370